Eo wa ako alangba kan , odidi atare kan , odidi atare aja kan , epo obo die , igi nla die , eso bomubomu kan , owu dudu pelu funfun ati pupa , epo pupa die , adin dudu die , isasun tuntun kan...SISERE... Eo mu ako alangba yen Eo ge orire Eo fi odidi atare aja ha lenu Eo la eso bomubomu legbe die Eo wa gbe ori alangba na sinu eso bomubomu Eo wa jopo Eo lo ebu yen daadaa Eo wa di sinu efe owu Eo fi owu funfun we daadaa Eo toju ikobere yen pabo...APAKEJI... Eo ge apa alangba yen mererin Eo jo pelu oko atare kan ninu atare yen Eo wa di sinu efe owu Eo fi owu dudu we Eo toju ikobere yen na pamo ...APAKETA... Eo wa jo oko atare meji toku pelu iru alangba yen ati epo obo ati igi nla yen Eo di sinu efe owu Eo fi owu dudu ati pupa ati funfun di daadaa ...TITORE... Eo wa aso funfun Eo ma di ikobere yen kan kan sibe Eo ma tani koko Yio je ona meta beyen Eo fise ifunpa ...NOTE... Ikobere yen ko budo kan ara won Ebudo t ani koko daadaa tiwon koni le kan ara won amo ojukan ni gbogbo won mawa Lara ifunpa yen ooooo amo Eo jeki ikobere yen fun arawon ni alafo (gab) daadaa kesi ri wipe eda oni ka luku mo daadaa ...ALAYE... Eo kan adin dudu die si ikobere Toni eyi toje apa alangba mererin yen Eo wa kan epo pupa die si eyii Toni epo obo ati igi nla yen ...NOTE... Ti eso bomubomu yen ni Eo nifi nkan kan ra Lara ooooo Eo wa sile kogbe daadaa ...LILORE... Eo ma fi sapa yin ' osise agbero ' owo ' ama fi ifunpa yi ko soju ona wa aye abi aje abi emere abi oso oniwa ba Ogun taba se je ...! ?

ARANMU ASIRI BIBO TODAJU

Eo wa okan aguntan oojo , Ikode meta , Iye agbe meta , Iye aluko meta , Iye igun meta , Iye owiwi meta ...SISERE... Eo fi aso eegun togbajumon di awon iye yen papo Eo ki owo eyo meta ailuju bo inu iho okan aguntan yen Eo wa wa fi awon iye ti a ti di papo yen bo inu iho okan aguntan yen ti enu awon iye yen ma koju soke ninu okan yen Eo wa pa ibepe dudu kan ni pansa Eo gbe okan aguntan yen sinu e Eo fi eku ago kan si apa otun legbe okan yen ninu ibepe yen Eo fi odidi atare aja kan si losi Eo wa fi ideri re de pada Eo di pelu aso waji Eo gbe sinu ape tuntun Eo wa ko opolopo ewe iranje pelu ewe afeloru bo monle Eo fi odidi awo okete kan bo odi jijo Eo ro sinu igo funfun Eo pa eje eyele funfun bo Eo gbe sinu apo aso funfun Eo gbe ko sigun ile...LILORE... Eo koko fi fo eko mun fun 16days lerawon Eo sese wa ma lo ni emeta lososu pelu fifo eko mun...AKIYESI... ti anu olohun batinde ki a ma se itore anu Dada fun awon alaini ...NB.... Eo so eyele ti a fi bo igo yen nu ni oooo...!

IMULE PELU IBEPE FUN ISORI TODAJU

Eo wa odidi adanripon kan , eyo atare merindilogun , abeere kan...SISERE... Eo ge lori lekan naa Eo fi eyo ataare merindilogun (16) si lenu Eo fi abere kekere kan gun lori ti yio jade ni isale re Eo lo ju sinu ibepe dudu ti a pa ni pansa lori iyare ti abati ki ori alangba yii bo ibe Eo baa da mejemu wipe emi lagbaja ba iwo ibepe yii munle loni Emi kotun fi owo ara mi ja eso lori re mo laye gbogbo eniti o baa ti npe gbogbo eniti o baa lo ninu ogun yii nibi laye ki ori bere sini fo won korun ma wo won Ki igbona ma se won. To badi aro ojo keji ao lo ja Eo jo ao gbodo si ibiti atipa ni pansa yen wo mo o Eo gbe sinu ape Eo jo ao lo kuna Eo yo abere ibe Eo da ebu yen sinu igo kan Eo da ebu yen si lori... LILORE... gbere meje fun obinrin, mesan fun okunrun ni arin ori abere yen ko gbodo sonu...AKIYESI... Eo si gbodo lo jaa ibepe mo lori eyiti a lo yen opo enia le lo awa nikan ni ao gbodo de idi ibepe yen kaa omo re mo laye...!ṣ

OSO ONI AGBON JENTEGBE LAYE TODAJU

Eo wa agbon odidi kan , owo akese die , eye alanpadede meta , eyin eyele meta ... SISERE... Eo gbe omi agbon (coconut) yen sibi kan Eo po omi yen Mon epo pupa Eo fi yika aro ti amafijo ise yi Eo wa ge agbon yen Lori Eo fi owu akese die te inu agbon yen Eo ko eyin Eiye alapandede meta pelu eyin eyele meta sori owu yen Eo ka gbogbo owo tanna roboto Eo gbe le awon eyin yen Lori Eo tun fi owu akese bowon monle Eo fi ideri ti a ge Lori agbon yen de pada Eo fi owu di Eo fi complete awo ologinni we dada Eo wa ko epo asorin die tele ape tuntun Eo ko epo obo die si ao wa ko epo igi ose tutu lewon monle Eo wa gbe agbon ti a ti we ni awo ologinni yen le Lori ao ko ewe ela Tutu bo monle odi jijo pelu odidi atare meta Eo lo kuna Dada Eo ro sinu sere Eo pa eyele alawo meta bo sere yen a le huhu re Mon tobasi wuwa a le ma le Mon ko bawi Eo gbe si aaye owo...LILORE... Eo ma fi foko mun ni emeta larin osu kan Sugbon idaji bi 5:00am ni lilo re ...AKIYESI... A le lo eyele ti a fi bo sere yen fun nkan Miran kosi laifi nbe rara...AKIYESI... Eo wa Eiye alapandede pelu atare aja kan Odi jijo Eo ro sinu ado ijamon ao fi nkan di lenu Eni tounlo ise yi ma toju e sinu yara ti ise yen wa Eo kan fipamon sibikan nani ooo kiise amagbe si ibi ti a yen si ooo kokanwa ninu yara tiseyen wa sha Ti ebu yen batitan Eo fi ebu inu ado ijamon yen foko mun lekanna tie ni opari Eo si lo sere pelu ado ijamo yen nu...!ṣ

AKO EYONU IMULE

Eo wa ikarahun igbin oju oosa , igba ahun , ipe oore topo , ipe akika topo , odidi atare kan... SISERE... Eo jo papo Eoro sinu ado ato kan Eo fi eje adie asa toti pamori ra ato naa ati lile iye mo Lara Eo mate ni osameji pelu ofore Eo mafi oti epo tabi omi lo....OFORE... oniye owewe,atobo joro, alagogo ni gban gihan, won ni ki awon aje oma fesuru pesuru, awon aje fesuru pesuru,won ni ki awon aje omafe osun aloran,awon aje fe osun aloran,won ni ki awon aje oma kala ejio,awon aje kala ejio,won ni ki awon aje oma fomode ile gba suje,awon aje fomode ile gba suje,won ni ki awon aje oma jale,awon aje gbe adie okengowe,won wa nsalo,won nle won,won wa sare gungi onto,won wa mi igi mowon,won wa Ja lule,won wa se lapa,won se lese,orunmila ni igba wo layeyin wa dojuru bayiṣ Onitabi eti gbagbe ni,nigbati enti ikole orun bowa si ikole aye,ti e de oritameta agbansala aye lotu ife,tomikun moyin ti eorona koja,ewa sare titi eloba ejiogbe , eniki ejiogbe wa gbeyin doke omi, ejiogbe ni ohun o le gbeyin doke omi,esare eloba oyeku meji kogbeyin doke omi,oyeku meji ni ohun kole gbeyin doke omi,eloba iwori meji kogbeyin goke omi,iwori meji ni ohun ole gbeyin goke omi,eloba obara meji kogbeyin doke omi,obara meji ni ohun ole gbeyin goke omi,eloba okanran meji kogbeyin koge omi,okanran meji ni ohun ole gbeyin goke omi,eloba irosun meji kogbeyin koge omi,irosun meji ni ohun olegbeyin koge omi,eloba owanrin meji kogbeyin koge omi,owanrin meji ni ohun olegbeyin goke omi,eloba ogunda meji kogbeyin goke omi,ogunda meji ni ohun oba gbeyin goke omi,sugbon Oro aso kan ni eledumare fita ohun lore wasi ile aye,tohun bafi ikan yi gbeyin goke omi,ohun ole ma rin ihoho,ewa sare eloba osameji tise ifa kewa,ewa ni kogbeyin goke omi,osameji lowa gbe awon aje koge omi ,ohun logbe awon eleye goke odo,orunmila wa ni gbogbo eyin eleye tebade ile aye,gbogbo ohun ti ba nse omo osameji ti edayeba ateyi tode bayin kilema se funwonṣ Won ni omo osameji tawon bade ile aye ba tabi eyiti obadele aye ba awon,won ni tikoba lowo awon o je koni,tikoba bimo awon o je kobi,tikoba Lola awon oje koni,tikoba kole awon oje koko,won wa ni omo orunmila tobati lowo nkoṣ Won ni toba lowo konirun,toba Lola koni run,toba kole koni wo,toba bimo koni Ku,won wa ni omo osameji toba ni Emi gungun koni kuru,toba ni Emi kukuru,awon o sodi gungun,orunmila wa ni gbogbo eyin eleye

gbogbo eyin aje,oni gbogbo adehun tese funmi

lemuse mo nkoṣ Won ni awon Oni wibe,onitie batie wibe Mofe ki gbogbo yin lomo pe,enikan ki je ahun koje igba ahun,enikan kije oore koje ipe oore,enikan kije akika koje ipe akika,enikan kije igbin oju oosa,kotun je ikarahun re mo,gbogbo ohun tiiba se tomo osameji Nile aye,koni se je funyin ooo Emi L omo L kinmase je foso,kinmase je faje,kinmase je felebologun , kinmase je fun emere,kinmase je fun alalufa,kinmase je fun alaweroko,kinmase je fun alawerodo, kinmase je fun alasan , kinmase je fun onigede , kinmase je fun alapepa , kinmase je fun alasapa , kinmase je fun alaroka, kinmase je fun apuromoni takoni, kinmase je fun gbogbo omo araye, osa meji ooooo,wa sare tete kolo sorigun mererin isalu aye,ko lore ko ire ola ire ola,ire owo ,ire iyi,ire agbega,ire alafia ...ANIYAN ADURA...!

SIGIDI AKO ABOHUNGIRIGIRI OSOLE GIDI TOSI DAJU

Eo wa edan onirin ako kekere kan , ori ejo oka tolase kan kan , egbo akerejupon die , ewe abamoda tutu , ewe aje sefunsefun , itagiri nla nla meta , okan abo elede tutu kan , okan abo ewure kan tutu , okan abo aguntan , eso werejeje meji , akuko adie kan , odidi atare kan ...SISERE... Eo mu itagiri meta yen Eo gun wewe ninu odo Eo wa ko itagiri tegun yen sinu Ikoko Eo bu omi si Eo se ko hoo daadaa Eo wa da Omi tefi se yen sibi kan Eo da sakiti itagiri yen danu Eo wa mu edan ako Eo ki senu Ori oka yen Eo fi sinu isasun Eoko egbo akerejupon le Eo tun ko ewe abamoda le Eo wa jopo Eo yo edan yen sibi kan Eo lo ebu yen daadaa Eo ro ebu yen papo sibi kan Eo wa fi omi tefin se itagiri yen po yepe amo Eo fi mo sigidi Eo fi oju olongbo kankan se oju re Eo wa ki edan yen sinu sigidi yen ...NOTE... ti edan yen obudo han sita rara ati rara oooo Eo wa sa kogbe daadaa Eo pa akuko adie kan le sigidi Lori ninu orun ti eba sa si yen Eo jeki eje yen na o gbemo Lara daadaa ti eje na batigbe daadaa Eo gbe sigidi yen wole Eo gbe sinu awo funfun nla kan .... APAKEJI... Eo ko awon okan yen sinu ape Eo ko ewe aje sefunsefun le Lori pelu odidi atare kan Eo wa jopo Eo lo ebu yen daadaa Eo wa da ebu yen mo ebu alakoko titi ori oka yen Eo mix re papo daadaa Eo da sinu adin dudu teti mix epo pupa pelu re Eo jeki opo gan ....LILORE ... Eo ma ta adin teti mix ebu yen mo sori sigidi yen pelu ..ANIYAN ADURA... owo gidi ni aro Hmmmmmmmm esi mari owo lagbara olorun .... AKIYESI... ti adin ti eda ebu yen si batan Eo ri sigidi yen mole sinu Yara yiii lobatan aje asi ma woleee fah...! ?

SO IMULE IGBEMI AWON AGBA

Eo wa adie agbebo dudu kan , odidi atare aja kan , igi nla , ewe iyalode mejeji , ado ijamo kan , omo okete tikotilaju kan , oyin...SISERE... Eo ko ifun re lati idi Eo jo ifun yen pelu odidi atare aja kan iginla die ewe iyalode pupa ati funfun Eo ro sinu ado ijamo Eo lo ri mo ori oro fun ojo meje Eo lo hu leyin ojo keje yen Eo jo pelu omo okete tiotilaju kan pelu ikan aguntan oojo Eo lo kuna dada Eo wa bu die ninu ebu yen sinu efe owu Eo di ni ikobere pelu owu funfun ti oba di ago mesan ale Eo toju awo funfun Eo da oyin si Eo wa so ikobere yen sinu e lati ago mesan di 3:00am oru tobadi 3 yen Eo di dide Eo ro aso funfun mondi Eo wa so gbolohun yi ...OFORE... agba nisilekun fun agba,eyin tolaiye esilekun ola fun mi o Eo se aduralekunrere Eo wa yo ikobere yen ninu oyin Eo so senu Eo gbemi Eo lo sun pada ti oba di 5:30am idaji laiti soro si enikankan Eo da ebu toku yen sinu oyin inu awo yen Eo la tan patapata Eo soro fun obinrin fun 16days...! ?

ORUKA OLUKUSUN TO SISE ASIRI BIBO RE

Eo wa igbin agbonu kan , oruka ide tabi eyikeyi kan , ewe abamoda eyo meta , ewe gbodogi tutu , owu dudu , ogiri die...SISERE... Eo fi oruka ide tabi eyi toba wuwa kan bo oju igbin yi Eo fi ewe abamoda meta bo igbin na loju Eo wa fi ewe gbodogi we papo dada Eo di ni owu dudu Eo wa so sinu omi gbona toba jinna die Eo yo jade Eo tu Eo ko ewe abamoda yen soro olo Eo lo Eo yo oruka yen sinu isaasun Eo fa ewe ti a lo si pelu ogiri Eo yo igbin yen na ninu ikarahun Eo so si Eo se lepo niyo toba tutu die Eo sadura si odi jije Eo ma fi oruka yen sowo asiri wa onitu...! ?

ASETA PONRI TO SINA OWO FUN NI

Eo wa ako alangba kan to pon daada kan , itanna sawerepepe to po die , ati moriwo ope...SISERE... E koko ba mi so alangba yi mo okun kan ki e wo kaakiri ki e fi se wahala to po sugbon e ma je ki o ku o e wa ba mi gbe alangba yi si ori saare ki e ba mi ge ori ati iru re ki e wa ge ara to ku si ona meje to ba je obinrin ni a fe se ise yi fun ona marun ni a ma ge ara yen si gbolohun yi ni E o ma pe ti a ba n se kinni yi lori saare yen o...OFORE...Iwaju aye awo aye lodifa fun aye Ikokotiri awo orun lodifafun orun agaramata awo olomo lo difafun olomo ni ojo ti awon ajogun n le olomo kaakiri aye olomo sa titi o sa de ile ira, won be awon jogun ki won pada, won ni awon ko nipada, olomo tun sa titi o sa lo idoromo awise, won be awon ajogun ki won pada, won ni awon ko ni pada won le olomo titi o di eyin odi ilu, olomo nke, o ni odi ilu kii je lu o tu, arabaraba kii je ki ilu osofo, ajogun ti n le mi bo yi, e pada leyin mi, olomo gbera o di ile orunmila, won de ile orunmila, orunmila ni eyin ajogun e pada leyin olomo, won ni awon ko ni pada, orunmila ni kii laa fi salejo ajogun, baba ba mu ponri lo ori eni ana, eni ana lo wa fun awon ajogun ni ponri je, won o le duro, won o le bere mo, won ni orunmila dakun dabo fiyedenu, awon ti fi olomo le ko mo o lo, ojokojo osukosu, igbakigba ti awon ba tun ki olomo mole ki eni ana o pa won, ki eni ana o se awon sibasibo, nje omo olomo ni lagbaja omo lagbaja, eyin ajogun e pada leyin mi sawerepepe ko maa pe gbogbo eniti o ba n di mi lowo sorun alakeji, sawerepepe ki o lo ma ba mi pe ire aye mi wa ba mi ...ALAYE... E o wako alangba yi sinu agbada Eo ko eso sawerepepe le lori Eo wa su moriwo ope ni osuka eyo kookan meje Eo ko le lori ti a ba jo tan E o lo fi sin gbere ooro (straight) mokanla si ori Eo ma fi eyiti o ku fo eko mu...! ?

IMULE OLOMUYEYE ASIRI BIBO

Eo wa agbebo adie dudu kan , ewe afeloru , ewe iyalode funfun , obi abata oloju merin meta , obi abata oloju meta meta , odidi atare kan , Igo epo pupa nla kan , Igo epo pupa kekere kan...SISERE... tobadi aago meje ale(7:00pm) Eo la adie yi laya laaye Eo gbe sinu isasun tuntun Eo je ki o ko aya si oke Eo ju atare si laya Lori ifun re Eo ko ewe iyalode si egbe otun adie yen Eo ko ewe afeloru si egbe osi Eo wa da obi na si ori adie yen gangan Eo wa lo gbe si ori panu di ojo keji pelu...ANIYAN ADURA... owo gidi taara pelu oruko iya t obiwa tobadi aago marun 5:00am idaji Eo ti dana sile Eo lo gbe ise yi Eo ni je ko kana o o di ori aro yen ... LATI ORI PANU SORI ARO... Eo fi epo pupa kekere yen yipo Idi aro yen Eo ma fi epo pupa keji sinu ise tanjo diedie titi Eofi jotan Eo lo tiyio kuna dada Eo ro sinu ado ato Eo gbe sinu aso funfun ko gbodo kanle mo ... LILORE ... Eo ma fi fo eko tutu mun laro laro...! ?

IMULE ATU IDIWO - EGUN TI ENIYAN FI NBO LOWO AWON MAMI

Eo wa eye oobe kan , odidi atare aja kan...SISERE... Eo jo papo Eo lo kunna soto obi ifin alawe meta kan Eo se lori Ina Eo yo kuro leyin ogbon iseju Eo lo kunna soto ojele ewe igi obiba tiko dalu meje Eo lo kunna Eo da gbogbo awon toku si Eo lo papo ni ihoho Eo ko sinu awo funfun Eo pa eiyele funfun tabi pupa tabi dudu balau kan si Eo fi ejere po papo ninu awo na Eo wa su sona meta Eo ma gbee mi ni ikookan ni ihoho omoluabi pelu gbolohun re Eo lo ri eyele yen mole sori akitan ki a to loo ogun yi...OFORE... Ile ni osho ati oobe ngbe, osho ko gbudo pa oobe je, beeni oobe kogbodo pa osho je, ile ni aje ati obe dijo ngbe, aje kogbodo pa oobe je, beeni oobe ko gbudo pa aje, emi lagbaja wa di osho loni, bi e ba ke ha , ma ke huu bi e ba kee huu, ma kee ha hu! nitori eiye aje kan ko gbudo ba lee igi obiba , aje kan koni fi obi sise bo orisa, emi ati yin di imule loni, ki e Ma di mi lowo, ki e ma ba nkan mi je, ki e ma pa mi je, ki e ma pa iyawo mi je ki e ma pa omo mi je gbogbo oogun ti mo ba nlo ki o ma je fun mi Eo ma so gbolohun yi si eyo kookan ti a ba ti mu dani ki a to min ni oo ti a ba ti min tan Eo wa mu hot lee lori daada ti oju wa yio ma po yi...NOTE....ihoho ni Eo se gbogbo oogun yi ihoho naa ni Eo loo oo ale pata ni Eo loo ti a ba ti loo tan Eo lo sun Eo gbudo jade mo rara Eo si gbudo sun ti obinrin ni ojo ti a ba loo Eo gbudo ba obinrin sun fun ojo meje gbako...ALAYE...ti a ba loo eyele funfun awon eleye funfun ni a ba se imule niyen ti a ba lo pupa awon eleye pupa ni a ba se imule bee si ni ti a ba loo dudu awon eleye dudu ni e ba se imule niyen Eleyi to dara ju ni ki a loo eyele funfun ...! ?

OSO OWO IRIN AJO OLA

Eo wa aso funfun tia ti ran bi ewu , ewure ti koiti bimo ri laiye , ibi omo tuntun , eiye kowe , Ewe orijin , ose dudu , owo eyo 41 , ileke ifun , eyin ibile kan...SISERE... Eo wo aso funfun yi ni dede ago kan osan ojo sunday, ao wa pa ewure yi ao gba eje re sinu ike kan Eo wa pa awo eran na ti apala osi , ao wa jo awo apala osi eran na tia ti pa pelu ibi omo yen eiye kowe ati ewe ferijimi , ao lo kuna Eo wa po po mose funfun a tun wa da eje eran na si Eo tun popo daada Eo wa ko owo eyo 41 yen pelu ileke ifun sinu ose ti a po na Eo wa gbe eyin adie ororo kan pamo sinu ose na fun ojo meta gbako to ba wa di ojo kerin Eo lo yo eyin yi Eo se adura si daada nkan tia nfe bi owo yen yio po to , ao wa se eyin na je ni ago mejila oru ose yi di wiwe ni gbogbo ojo , yato si ojo sunday ...NOTE... aro ni ao ma we ose na aso pupa ni ao fi ma bo ose na gbogbo nkan tia bere sori eyin adie yi , yio wa si imuse laarin osu meta o peju eran tia lo yen saara ni ao fi se eran ewure si di eewo fun wa latojo tia ti bere sini we ose na aso funfun tabi pupa ni agbodo ma wo ju Eo si gbodo je eyin adie fun osu meta bibeko gbogbo ola ati oro tia kojo ni yio parun tan obinrin ko gbodo de ibiti ose yi wa , bibeko ko ni bimo mo ...! ?

ASIRI TI AFI MA NPA EEGUN RUN TI AFI MA NWE OSI DANU ATUDE NI IDIWO NI - EYONU AWON AGBALAGBA

Eo wa eye onbe kan, eye adan kan, ewe peregun oojo ati egbo re, ewe tude oojo ati egbo re, eso laara pupa, Koro owu akese die, epo obo die, eje malu oojo, ose eyikeyi toba bawa lara mun...SISERE... Eo gun awon eroja yi kuna daada pelu ose eyikeyi toba bawa lara mun E o fi eje malu oojo po ose na po E o ko ose na sinu igba olomori tabi ike funfun olomori E o loma fi ose yi we ni odo ti o nsan. Ti aba ti fe we, a o koko fi odidi eko elewe kan pa gbogbo ara lati oke dele, a o wa we ose na si pelu kainkan ibile E o ju kainkan yen si odo Bayi ni a o se mawe ose na Emeeji ni ose ni ama nwe. Anytime ti aba ti ri wipe nkan kolo deede Eo bu lara ose na Kosigba ti akole fi we Eyan le we ose bi emeesan lera sugbon ko gbodo ju eekan tabi emeeji lose lo ti a o mawe ose na ni aarin ose obinrin le we ose na lera fun bi emeeje ni tie kio to dawo re duro na. Opo eyan le lo ise yi sugbon E gbodo mafi eko para ki eto we pelu kainkan kan fun iwe kan Eyan ko gbodo we ju ekan tabi emeeji lo ni ose kan o. Ojo Sunday, Monday, Tuesday ati Thursday lo dara ju lati pick fun iwe na. Anytime sini a le lowe iwe na si odo...! ?

OSOLE TODAJU FUN ENIKENI TABI OMO YAHOO

Eo wa odidi eye kowe toni ifun ninu ti ifun re ko iti jera tabi tutu kan, odidi eye ologesa Kan ti oun na ni ifun ninu, opolopo eso werenjeje , odidi atare nla kan ...SISERE... Eo jopo, ti a ba n jo lowo Eo mata epo pupa si ori okuta adiro meteta titi o fi ma jotan E o lo kuna daada a o ro sinu ado ti o bale gba...ETUTU RE ... Eo wa odidi ewure abo kan ti ko iti bimo ri ti a ba njo ogun na lowo, ori iso ni ewure yen mawa ti aba ti ro ogun na sinu ado tan Eo fi ori ewure na kan oriwa ni emeta, iyen ori eni ti o ni ogun na ao tun fi ado na kan eran yen lori ni emeta E o so wipe eyin aye, eran yin re oooo, ki e mon pami lomo ooo, ki esi mon pami laya ooo ki eje ki emi emi naa timo se ogun yi gun o E o pa eran a o ha eran na ni saara ni adugbo eni ti o ni ogun yi ko gbodo je ninu eran na ti o bawu awon family re won le je nibe, kose nkankan E o mafi schnap gidi lo ebu ni araro kutu hai, ki ato fohun siyan pelu adura. Kosi aburu fun awon ti won ba je ninu eran na o E ko gbodo fi eje ewure na pa ara ado na o Enikan ni ise na wa fun walahi Ise to daju saka ni ise yi ti o base wa di eyan nla, try lati ni ise atude awenu eyonu ati imunle Lara o Ise yi kosi fun ogberi ti koni lakaaye kikun lori ogun sise o...! ?

ASINA OWO NLA TODAJU - O TUN SISE EYONU OWO PAAPA

Eo wa ado ijamo meta E o ko ado yen tele ape Eo ko owo eyo meta ti ko loju le lori pelu ori agilinti kan tope daada E o fi odidi atare aja kan si E o jo a jo po E o lo kuna E o ro sinu seere nla kan, a o fi ewe ekuya tutu di enu seere na a o gbe idi seere yi sinu bonu epo pupa fun ojo meta, ti oba di ojo kerin, E o gbe seere yen lati inu epo pupa, Eo gbe sinu ape, a koni yo ewe enu re o, a o ko eyin pepeye kan ati eyin ororo meta E o jo a o lo kuna, a o ro sinu seere miran, a o fi ewe ajeobale di

lenu, a o gbe sori panu ile wa tabi ori paanu kitchen monju, ori paanu saani o gbodo wa lati ale monju a o gbe ni aro kutu, E o tun gbe sinu ape Eo jo pelu ewe eyin olobe tutu, ewe odundun, pelu odidi atare nla kan, a o lo kuna, a o sese wa ro sinu seere keta Eo pa eyele funfun kan bo seere na, a o fi eje re pa ara seere na. E o din eran eyele na, a o fise Saara, a ko gbodo je nibe...Eo wa iye okin meta, iye igun meta, iye lekeleke meta po pelu owu funfun...SISERE... E o fi idi iye yen se ideri seere yen, a o gbe sinu asunwon aso funfun E o gbeko si ara ogiri igun yara wa...LILORE... Eo mafi ebu na fo odidi eko elewe kookan mun ni nu igba olomori tuntun ni dede ago kan oru pelu adura owo nla...NOTE ... eyin ojo keta ta pari ise yi ni ama bere lilo re...NOTE... Emeesan ni E o malo ise na laarin osu kan Eo jeki o ma bosi ojo Monday ati Thursday... NOTE... ape tuntun kan ni ama lo fun jijo ise yi...SARA RE ... E o mafi agbado funfun se saara fun awon onibara ni ekookan toba rowa lorun, emeeji losu ni emi ma nse o. Enikan ni ise yi wa fun, looto ise yi ni wahala die ninu lati se, but ise yi dara gan, ti yio si so eyan di olorire laye...!

IDAUNDAN IJAKUMO AGADAGODO AYARA TUDE

Eo wa padlock tuntun Kan , Ikarahun igbin nla totobi daadaa kan , awo sobi tuntun nla kan , gbongbo ajeobale tutu , gbongbo tude die , ewe akoko oojo , Iginla die , Epo obo die , ewe ejinrin tutu , ewe ewuro oojo , oro agogo tutu , ogiri ijebu die , ewe iyaolode funfun die toojo , ewe iyalode pupa die toojo , Iku ojia , Epo pupa die... SISERE...Eo koko lo ra padlock tuntun Kan Eo wa fi padlock yen si igberi wa nibi ta sun si Eo gbe pillow lelori Eo gbe ori le Eo sun ti ile ba timo Ekogbodo ye padlock yen wo nibi to wa yen Eo wa lo gun gbogbo eroja yen papo mo ose Eo fi nkan luu ikarahun yen nibi to ma rorun daada lati padlock yen bo Eo wa lo mu padlock yen ni abe pillow yen ao wa sii (open) padlock yen Eo ki bo inu iho ta luu si ara ikarahun yen Eo wa tii (lock) pa Eo ko ose yen sinu ikarahun yen akogbodo yo omo key yen kuro Eo wa gbe sinu awo sobi yen Eo wa da epo pupa sii ti epo yen ma po ninu awo sobi yen ati gbogbo ara ose yen mon ikarahun yen...WIWERE... Eo ma sii (open) padlock yen tabati fe we ose yen taba we ose yen tan Eo ma tii (lock) pada Eo ma we lale patapata ...AKIYESI... ale ojo Tuesday lao fi padlock yen si igberi wa aro ojo Wednesday lao sise yen ale ojo Wednesday ta sise yen gan lao da epo pupa si ori re ale ojo Thursday lao bere wiwe ose yioo...IKILO PATAKI...taba nwe ose yen lowo ao ma di oju we ose yi nioo Epo pupa kogbodo tan lori ose yen ati ninu awo sobi yen won gbogbodo tii padlock yen mowa taba nwe lowo...SAARARE ...Eo fi akara elepo se sara kato bere wiwe ose yen Eo ma we ose yen pelu adura asina atude...!

MULE TI AWON AGBALAGBA FIN SANU YAN

Eo wa ori musu meta , ori ewure ibile dudu tope kan , eye kowe dudu tope dada kan , odidi atare nla kan...SISERE... Eo to sinu agbada ijo kan bi ase to si oke yen Eo jo papo tia ba jo tan Eo lo kuna dada Eo to sibi kan Eo mo lo ni ago mejila oru 12:00am Eo bu ebu yen bi igba kan abi abo kan Eo te ni IFA ODI MEJI Eo pe gbolohun re si to aba pe gbolohun e tan afi foko tutu mu eyan pupo le lo ise yi...OFORE... oso Ile iba yin o,aje Ile ibayin o,ori kun kun lewure fin la leja,kowe de aiye aje gbo de,eye keye ko gbodo ke mon,iba eyin iya mi osoronga apani ma wa gun olokiki oru,atile atona lafin ji ologbo , atile atona ni ki e fijin mi loni, esi ju anu womi,eyin to laye...NOTE... ihoho omo luabi ni alo ise yi kie si fi eyin to ogiri...!

ASIRI SANKISANKI OLUMERE OBA AJAKA AWORO

Eo wa eyele funfun aye meta , oga aye meta , Irun iyamopo die , tangiri meje tope mesan , ewe atewogbore tutu , ewe ewuro oojo , ewe ola die , egun ori esin die , owo eyo tikoluju 41 , igo epo kan , Igo oyin kan , pali sugar st Louis Kan , Iyo kongo kan , omo elede Kan , ori agbe Kan , odidi atare Kan , agogo , owu dudu atu funfun...SISERE... Eo koko fi tada ko oruko ile ise wa si abiya eyele meteta, ao wa ko m iru iyamopo sinu ewe ola Eo wa fi egun ori esin die lelori amEo di papo Eo wa gbe sinu ewe atewogbore tutu Eo wa tun di papo dada ao wa laa inu eyele funfun Kan akoni je ki ifun re ko ja kuro Eo wa fi nkan ta dii yen sinu eye yen Eo wa gbe ori agbe yen lelori ati oga aye Kan ao wa ran Ni owu dudu ati funfun Eo wa gbe sinu ape ijogun Eo fi atare Kan si legbe ao wa da ewe ewuro oojo bo moleb Eo jo papo taba ti jo tan ao da ebu yen si ona meta Eo da idakan sinu agogo yen ao wa handkerchief ti akomo eni toni Eo fi cover ori agogo yen ao wa dii lowu dudu ati funfun Eo wa so ko enu ona abawole shop tabi office wa...APAKEJI... Eo mu eyele keji ao laa inu re ki ifun re ko

Ni jaa kuro Eo da ebu keji yen sinu re ao wa ko owo eyo 41 sinu re Eo wa gbe oga aye keji sinu re ao ran pa ao wa gbe koto si enu ona abawole shop tabi office wa ao koko fi iyo yen ti inu koto yen Eo wa gbe eyele yen sinu re Eo wa to tangri meje tabi mesan yipo eleye yen ninu koto yen Eo da pali sugar st Louis Kan lelori Eo da epo pupa igo Kan lelori, ao wa da oyin gidi igo Kan lelori Eo wa pa omo elede lelori ti eje re ma mu ori dada Eo wa dii pa ale fi cement re pa Eo wa ge omo elede si ona merin elo bo mo origun shop tabi office yin nita..APAKETA ... Eo laa inu eyele yen keta ti ifun re koni ja kuro Eo da ebu keta yen sinu re ao wa gbe oga aye keta yen sinu re ao ran pa Eo ju sile ko ma lo sugbon ti koba le lo mo Eo lo fi ogbon ju sibiti ero ma npo si dada Eo ma bo ni ile...AKIYESI ...agogo ti won ti luu kakari lama lo oo tabi kara tuntun ka fun awon omode ki won ma lu kiri fun ojo meje tangri yen meje fun obinrin mesan fun okunrin ni ooo larin 21days Eo ri ise re ...!

IMULE OSO TODAJU

Eo wa odidi eye kowe nla kan , odidi eye owiwi nla kan , eye elegesa ojulowo kan , ori eye akalamagbo kan , iye agbegbere 11 , Iye aluko 11 , Ikode ojuda 11 , obi oloju merin pupa ati funfun kokan , ewe anu , ewe afoleru taja lojo , ewe mafowokomomi , ewe orijin...SISERE... Eojopo ninu ape tuntun kan Eo lo kunna dada Eo da sori opon ti won tifi Kiri ate ri dada Eo teni osa meji Eo PE gboloun resi...OFORE...gbogbo eye ni pejo rofun eye owiwi 3*, bi gbebogbebo bagbebo laye ale leye akala gbe rorun 3*, bi oku baku kowe nitufo re 3*, ewe orijin Loni ki gbogbo aye odari owo jo sI odo emi lagbaja omo lagbaja opari Eo ro sinu akeregbe kan Eo gbesi origun yara...LILORE... Eo mafi fo eko tutu mu Ni ale...NOTE...akogbodo fun enikeni lo ninu ise yi laisan owo toto idameta owo ise yi sugbon opo eniyan lelo...!

ASIRI OSO IDAKOMU

Eo wa eku asin meje , oga gbigbe tope meje , ako alangba tope meje , odidi atare nla meje , obuko tabi eyekan kan , ewe ola die , Eo ran aso tuntun kan aso yi ni Eo wo titi Eo fi pari iseyi Eo Lora ikoko tuntun kan...SISERE... Eo ko ewe ola topo tele ape na Eo ko olori owo ti won ba n na ni ilu ti abawa meje le Lori Eo koju won soke Eo tunko ewe ola

Stopo le mole Eo ko eku asin meje le Eo ko oga gbigbe meje le Eo ko ako alangba meje le aoko atare meje le Eo se adura sI Eo tun ko ewe ola le mole odi jijo sugbon Kato j ise yi Eo so odidi obuko kan tabi eyele dudu kan mole ni tosi odowa titi Eo fi pari ise na Eo lo kunna Eo ro sinu seere kan...LILORE... Eo mafi fokomu ni agokan oru pelu adura...AKIYESI... ti eran tabi eyele ti aso mole baku kato pari ise yen Eo losi bi oku ni sugbon ti koba ku Eo pa ao fise sara . . . !

IMUNLE AWON AJE PONBELE

Eo wa opolo gbigbe kan , alakan gbigbe kan , odidi atare kan , Eesan abo kan...SISERE...Eo gun papo Eo wa lo daada Eo mo bu si bi kan Eo wa te ifa osa meji si Eo wa pe gbolohun re si...OFORE... Babajakan 3* ako lodifa fun baba toko Ile,toko ojure seyin kule awon eleye iyami aje,woni Iwo babajakan,Iwo babajakan,Iwo baba jakanjakan,woni awon eleye yio ni je kogbe Ile re,oni ironi,ohun lohun yio gbe Ile ohun ti ohun ko,ohun lohun yio se baba omo hun to hun bi,ati iyawo hun,ohun ni ohun yio lo gbogbo dukia ohun ti ohun ni,oni bebe ni atare bo omore ,ero ona kiya Ile alakan kobo mi mu, agbalagba ilu won ki pejo ,ki won fi eran opolo se eran aparo,bi obinrin ba pa ekuro,abo eesan re soto ni, gbogbo eyin eleye aje oo,eyo ti emi lagbaja omo lagbaja soto ema pami lapapin,emo pami lapata,ema pami laparo,mo ba yin mule loni eko gbodo tami o,ao dasi enu,ao fi omi lo ni ago mejila oru ko ja dada...NOTE... Ema fun omo ti ojo orire o ba ti koja ogun odun lo ati obinrin agaga ko tun loyun walahi ti e ba fun won lo won di awon eleye ni agbako to wa wabe ni pe ti awon mejeji ba di eleye tan akoko ise won ni eni to gun won ni ye...!

ASIRI MAFI OWO KAN MI

Eo wa ekuru funfun kan , obi oloju mefa , igbe ti ewure ya lojuwa , Eyo atare kan...SISERE...Eo fi obi oloju mefa sinu ekuru funfun Eo fopo morawon Eo gbe pamo sibi toni owo dada Eo ti horo atare kan bonu igbe ti ewure ya lojuwa Eo fi

Ounna pamo sibi Toni owo dada tobadi ago kan oru ojona Eo dide ao lo igbe ewure ye pomo atare ti atibo inure ao fisin gbere eyokan siwaju oriwa leyinna ao wa bere sI je awe obi towa ninu ekuru ti afopo Ni eyo kokan Eo je merin nibe Eo ko meji toku pamo Eo lofan ekuru ye sita tobadi ni oworo kutukutu Eo lo bo awe obi meji toku mole lobapari gbogbo eni toba nawo aburu sie Ni won ma bomole kiakia asiri nla nio...!

OSOLE OWO TODAJU

Eo wa pepeye funfun ako tabi abo nla aye kan, alangba oojo ako meje, alangba oojo abo meje, odidi atare nla meje, ewe ola pupo , ape ijogun tuntun kan, igo funfun kan, oti Lord tabi Schnapp original kan...SISERE... E o du pepeye yen sinu ape E o gbe sinu ape yen a o ko alangba yen le lori a o ko atare si a o wa da ewe ola bo monle daada E o fi epo pupa round aro na ati si ori okuta aro meteta a o gbe ape ka ina, a o jo a o lo kuna, a o ro sinu igo funfun yen...LILORE... Eo bu die si owo osi wa E o sadura owo si Eo fi oti lord tabi Schnapp aro kutu hai ki ato soro siyan ni lilo re o ojojumo sini a o malo titi a fima ri owo yen pe...AKIYESI.... Eni kan ni ise yi wa fun o nitori eyin oloju aanu ti olorun bani ki ise yi ba e lara mun, 7times ni yio fi mun 50k wa making 350k. Ti owo yen bati wa pe 7times a ma da ebu iyoku nu ni o ko wulo mon...NOTE... mio so wipe 7times ni wa fi lo ebu na o wa ma lo titi owo yen fima wa pe 7times ni o...! ?

IMUNLE AKEKAKKAA AWON AGBALAGBA TI WON FIMA N SI ONA OWO - AJE FUNYAN

Eo wa eye lekeleke kan tope daada, eyele funfun aye kan, eyele dudu aye kan, adiye opipi kan, ewe alupaida topo daada, oga gbigbe meji, odidi atare nla kan...SISERE... Eo du eyele mejeji ati adiye sinu ape E o meteta tele ape E o gbe lekeleke oga ati atare le lori Eo da ewe alupaida bo monle E o fi epo pupa round aro a o bu die die si ori okuta aro meteta na E o jo Eo lo kuna lori olo E o fi gbogbo ebu yen te ifa eji ogbe sori olo, a o pe ofore si leyin ofore E o ro sinu ado seere kan E o gbe ko si ibi kan ninu yara wa ti idi re koni kanle, a o mafi fo eko tutu mun ni ago kan oru Enikan ni ebu yi wa fun o Inu asunwon aso funfun ni mogbe temi si, sugbon kiise dandan, ki idi re sati ma kanle ni...OFORE... Akekakaka 3* Akekakaka loruko ti anpe eyin iyami eleye, eyin aye, e gbami o, sebi Akekaka ni won fi mun ato meji ti nbe lorile aye, ato mejeji yi ni eledumare fi ran orunmila losi odo awon eleye, orunmila ni eyin iya mi, se ki n wole, won ni ti o bati wole, kio ke kaka, kio mun lekeleke alaso ala, tohun ti oga meji, ati ewe alupaida ati eyele funfun ati eyele dudu, awon ni ebun ola tabi oso ola re, ona asi la peregede, ona yio si fun o, ona yio la fun o o, egun ata kigun ata denu, ajimorisan ooo3* ebun ola, jade losi gbogbo aye, ki won dun gbonran gbonran gbonran, ki owo nla nla wa ba emi L O L lati oni lo, ki n ma nakan tan, ki nto mari omiran, ki aye ma mun mi, ki aye ma mun omo mi, ki aye ma mun aya, ki ona misi, ki ona mi la o obinrin kole lo ise yi, kosi okunrin ti kole lo agaga eni ti ona ba di mon gbogbo awa ti anda eyan lohun na le lo ise yi...! ?

OSO KUNUKUNU

Eo wa okan inaki meta ojuda , opolo ooye meta , oga ooye meta , odidi atare meta , 1000 tuntun meta , dollars meta , isasun tuntun meta ...SISERE... Eo koko jo okan yen kan ati opolo kan oga kan odidi atare kan owo tuntun kan dollars kan ninu isasun kan Bee na ni Eo se elekeji ninu isasun elekeji bee na ni Eo se se eleketa ninu isasun keta amo ojo kan soso ni ama jo meteta ooo Eo wa lo ebu na wo obudo kan ara won oooo...LILORE... oru meta ni Eo fi lo ise na ni ago kan oru isasun keji ni ago kan oru ojo keji isasun keta ni ago kan oru ojo keta pelu otin shirnapp onigun merin la ma fi lo ...NOTE... eje kani imule gidi lara nitori oso yii ma si owo muwa ni ...! ?

IFERAN EJIOGBE FUN YAHOO - BUSINESS - ABI CONTRACTOR - WOLI ABI ALFA - ABI ONISE OWO

Eo wa adanripon kan , oga tutu kan , ewe alupaida , ewe omisinmisi , ewe anu , ewe afaimonikonimora , epo opoto , ewe jeminiho , ileke itun , ileke ifa , perfume onala nla kan ...SISERE... Eo gun adanripon mo oga tutu papo Eo wa sese gun mo

awon eroja toku yen Eo wa pomo nkan ti ekokan gun meji a koko yo yen Eo wa perfume onala nla kan Eo da onala yi si ona meji Eo da ebu yi na si ona meji Eo po apakan ebu yii mo ose funfun eyikeyi Eo wa da perfume yi die mo oseyii Eo po papo ti yio ro daadaa Eo wa fo eyin ororo kan mo Eo po papo Eo fi ori aparo kan sisale ike funfun kan Eo ko ose yii le lori Eo wa da ebu apakan toku yi sinu perfume onala toku yii Eo gbe papo fun ojo meje abi mesan lehin na Eo ma fi owo alafia bu ose yi nihoho pelu ofore Eo wa ma bu oseyi lowe asi ma pe ofo yi tiaban we oseyii ti aba wetan Eo lo di onala yi para ...OFORE... iba 3* iba ajagunmare oluwo ode orun , iba akoja ewe , iba akowa egbo , ajipa iku mope , ajioarunda mope , aluipada koni kie mase pahunmida , odolupefelake , odoropepa aje loko , imu sese tin be lokun kosuretete jeminiho temi , ase talagemo papa lehin alujonu tin gbenu afefe ngba , mopase kitomode tagba kiwon mafi gbogbo ohun rere jimi loni , enu okere lofin poloko niju ki tokunrin tobinrin mafi owo wa npemi , maye 3* mase 3* mako 3* , olugbo ki kohun ase igbo , olu ile kikohun abemi , oritameta ki kohun esu odara...! ?

OSOLE EYONU DABIRA

Eo wa odidi eye igunnugun kan , iye agbe mewa , iye aluko mewa , ikoide mewa , ori ologbo kan , ori oka kan , ori ere toje tutu kan , ata ijosi ekunwo kan , aso funfun die... SISERE... Eo koko ro ata ijosi yen senu ori ere Eo wa fi aso funfun dipo daadaa Eo fi rori sun lalt ti aba fesun bi ogun yii yio ba sise oju orun laotimo ti aba ti la ala daadaa Eo tun aso yen sile Eo da ata yen kuro lenu ori ere na Eo jo gbogbo won po ati ata ati ori ere pelu gbogbo eroja toku Eo po ebu ye mose dudu pelu eje eran obuko togbo daadaa Eo gbe ose sori aso funfun opa meji Eo soko si igun ile idi re obudo kanle mo ...LILORE... wiwe lehin ojo medogun lehin tiatise iwadi ohun ti ose na yio gba...! ?

OSHA IYA SEKETE

Eo lo ra ere obinrin to kunle eyiti o gbe igba dani Eo wa eye owiwi kan, odidi atare kan, iye igun meje , iye akala meje, ori olongbo to ni irun eyokan... SISERE... Eo jopo Eo ko nibere pelu owu dudi ati funfun Eo so mon ere yii ni abiya otun....Eo lo ra eye obe,ori oyo,odidi atare aja kan,iye igun mesan,iye akala mesan,ori olongbo tutu,ewe orijin,ewe mafowo kan omo mi,esuru pupa,ata ijosi,epo obo,epo iginla,ewe afeloru 16, Eo jopo,ao fi die Lara ebure kobere pelu owu pupa ao so mon ere yii ni abiya ose, ao fi ebu toku po ose dudu to po Eo le mo ori oyan ere yii....Oju eye igun meji,oju olongbo meji,oju eyekalapangede meji,ao koko yo oju otun awon kan to no ka so oke yii ao lopo Mon omo atare kan ao fi oyin die po ati omi,ao ko mo ose kekere,ao me mo oju otun,ao lo ti ose be sugbon eje adie akuko ni ao fi po ao le Mon oju ose ao wa fi eje akuko yii fa omije wale lojure ose....abo adiye toti pa ri kan , iye igun meta , iye akala meta , awo ori okete die oko atare kan,ao gun po Eo pa ediye yii,ao ro eje re die so ori ere yii ao tu irun ayare,si ori ere yii,ao wa fi owo le ebu ti agun yii mo Lori Eo wa igba kekere kan ao GBE si inu igba owo iya yii Eo da omi oronbo si,ao fi edun ara kan si,ao gun egbo ipeta akogun epo akoko,ewe eyin olobe,etiponla eedu aaro, ewe iyeye Eo da sinu omi orobo yii ao de pa,ao wa da aso pupa bo monle, ti abati fesi aso yii,ao pe gbolohun re si...OFORE... iyasekete,awo ode egba3×,oni Iwo yio wo ile orunmila de, to barode awo,oni Iwo ko ni jeki aisan kankan kolu omo orunmila,oniti aisan ko bamo toba fowo bawon oniwo yio fi agboo owore mun won ti arawon yio ya,oni Iwo yio fi ose ayare wewon ye wa we omoreye loni ooo ,ao wa si aso pupa yii...LILORE... Ti obare yan ti eba tiri wipe ki se oju lasan ebu die ninu agbo yii ki e fun mun ki e wa bu ose yii fun ko fiwe si Oriya meta lekan tabi eniti aye ba ndilowo ebufun kofiwe kolo da omi I were sorita meta Ti obirin bafe wo egbe imunle,efun ni eyokan ninu iye ori oosa yi ko fi ha irun re lale o ni je ki ose yii tan ti ao fi ma le ose lasan mon, agboo owore na ao ma fi omi orombo paro (top) re ..!

IMULE AWON MOMMY

Eo wa igbale idi kan , olongbo dudu tope Kan , opolo , ijokun meta , ewe ogege tutu 21 , eku asin meta tope , oga gbigbe tope meta , eso idoo eyo 21 , opolopo eso werenjeje , odidi atare meta , epo obo to gbo dada , epo pupa igo Kan , oti schnapps igo Kan , aso funfun... SISERE... Eo pa olongbo yen ti eje koni jade Lara re Eo wa gbe sinu ape ijogun tuntun Eo wa ko eroja to ku lelori Eo pa epo obo pepe ao ko epo obo yen le awon eroja yen Lori ti epo obo yen ma bo awon eroja yen

mole Eo wa fi epo pupa yipo aro kaa Eo tun fi oti schnapps yen yipo aro yen ka Eo wa jo gbogbo re papo taba ti njo awon nkan yi ao ma taa epo sinu Ina Eo si ma ta oti schnapps yen si ori aro ati ilele taba ti jo tan ao da ebu yen si meji Eo po idakan mo ose dudu tabi ose ghana ao ko si ori enu igbale yen Eo wa da ebu yoku sinu awo sobi...OFORE... ifa rowa 3* elarowa 3* ojuponmi kankan kin to mo ifa mosalo salo kintoomo ogbedi aalo , to dafafun won ni ilu ogege, nibiti wonti dajo Eesu (contribution) Eesu ti wondanibe omo won ni won finko ,won pa omo alaraje ,wonpa omo ajero je,osa meji eyin ni mo wa di, nitoripe ijeti aje eran gbogbo enikan kiije oga bee, ijeti aje eran gbogbo enikan kiije eku asin bee,bi ase nje eran gbogbo akogbodo je ologinni bee, ijeti aje Ohun gbogbo enikan kiije werenjeje bee, ijeti anje ohun gbogbo enikan kiije eso ido, jeti anje ohun gbogbo enikan kiije atare bee ,ti aba ngba ile sele nteri ba mo teriba fun eyin iya ooo, oso ile imule yin ni monse, aje ile imule yin monse, akiibani mule katun pani ,aki bani mule kadini lowo, akiibani mule katun ba aye enije ,aki bani mule katun da oro eni ruu, eyin iya ooo 3* sebi ti yin Ni mo nse, ao wa ma te ifa osa meji SI ori ebu yen kato pe ofo yen Eo wa ma bu oju ifa yen ....LILORE... Eo ma fi epo pupa lo ni ago meta oru Eo ma we ose yen na ago meta oru Eo koko fi igbale yen gba ile fun ojo meta Eo tu okun (rope) ti won ba fi di igbale yen loja Eo wa fi aso funfun dii pada Eo wa fi gbale fun ojo meta...NOTE... Igbale alagbon (coconut) ni Eo lo fi siseyii ooo ...!

ORO NIPA ONKOWE YIII PELU AKIYESI ....!!!
KOSI NKAN ARA ENIYAN - (HUMAN BEING PART) - NINU IWE YIII....ITORI WIPE OLODI SI OFIN IJOBA ATI OFIN ELEDUARE PELU .Emina ni oludasile alase - **TEMIDIRE INTERNATIONAL HERBAL RESEARCH VENTURES** ....08165687477, 09053273312..!!
inu Mi dun pupo fun oore ofe ti eledumare fun mi fun kiko iwe ti ape , oruko ni **ATARI AJANAKU**...looto ni ogbon inu Agba ni eyan finpe lase , mosi ki eyin baba Mi ati iyami fun aduro timi ni gbigbe abi tite iwe yi sita , ope ni fun eledumare oba asake aiye oba asake orun titobi re eledumare , eni toba ni ogun tikoni asiri koti ni nkankan , enibawa ni ogun ati asiri tiko ni imo nipa re , kole molo alagbara tikoba she suuru tikoni imo ile ayoooo , je kani suuru ninu aiye nje odidi dandan kaje eyan (human being) kato di eniyan laiye koribeee orisirisi ona alegba latidi oloro olowo laiye ...laipe eniyan abi lo nkan ara eniyan (human being part) ...Ara tuntun ni mogbe oooo... Toh oruko koyinpada **OLAFOJUHAN SAMSON** ...Omo ogunlana , moje Omo Bibi ipinle osun state ni agbegbe ... **IPETU IJESHA** .... Timosi je Omo odun Ogun (20 years) .. Timofi te owe yiii sita looto mole kere loju amo ogbon inu Agba nbe ninu Mi ...odun merin (4 years) - ni mofi rin nipa egbogi abi nkan asiri aiye topamo ti mosi dupe lowo eledumare wipe momo nkan ti mofe mo , mosi ko eko nipa nkan ti mofe ko ...ope ni fun eledumare ... !! ajogun ba niseyiiii ..ki olorun fi alubarika si ...moko eko lodo baba tobi mummy tobi mummy Mi ...emina sirin nipa eko ati akiyesi ninu ninu herbal reaserch ...nimoyan lajo .....moti beere nipa irin ajo bayiii ni gba timotiwa ni ..(16 years old) - olafojuhan3@gmail.com ..!!!! Ti eledumare sifi adura si...!!! 08165687477